Ọkọ Oju-omi Kan Ri Si Arin Okun


# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 586 WEDNESDAY APRIL, 22 1964 (2D)


## Ọkọ Oju-omi Kan Ri Si Arin Okun

PAKISTAN:— Idaamu nla ba gbogbo awọn ero mọkanlelogun ti nwọn wa ninu ọkọ oju omi kan, nigbati ọkọ na de arin agbami okun ni ilu kan ti nwọn npe ni Dacca, ti o jinna si arin ilu ni nkan bi ọgọrun ẹsẹ bata, ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi.

Irohin awọn alaṣẹ ọkọ oju omi fi ye wa pe, ọkọ oju omi na nko awọn ero ibi iṣẹ bọ wa si arin ilu lati Ebute kan ti nwọn gbe lọ ṣe iṣẹ, o si ku diẹ ki nwọn gunlẹ si Ebute, ni ọkọ-oju omi na ba duro ti ko si le lọmọ.

Bi awọn enia na ti fẹ mura ki nwọn si wo ohun ti o ba bajẹ ninu ọkọ oju omi na, lojiji ni awọn ri ti omi ti nwọ inu ọkọ oju omi na, nwọn ko si mọ ohun ti nwọn le ṣe. Lẹsẹkẹsẹ ni ọkọ oju-omi na ba bẹrẹsi iri lọ si isalẹ odo.

Enu ya gbogbo awọn enia ti o duro si Ebute lati ri wipe ọkọ oju omi ti awọn nwo ti o mbọ ni ọọkan ko si loju omi mọ, o si ti ri lọ si isalẹ odo.

Irohin na fi ye wa wipe, enia mẹsan ninu awọn ero inu ọkọ na ti o mọ wẹ ni nwọn wẹ wa si Ebute gbogbo awọn enia yoku ni nwọn si ṣegbe sinu odo na.

A gbọ wipe, awọn Ọlọpa ti nwa inu odo na lati gbe oku awọn enia na jade bẹni awọn alaṣẹ ọkọ oju omi na nwa ọna lati gbe ọkọ na jade, ṣugbọn nwọn ko ti mọ ọna ti nwọn o gba lati yọ ọkọ na.

## Ọgbẹni Ọdẹsanya Sọ Pe :

# ADAJỌ ṢI ARA RẸ L'ỌNA

EKO:- Ọrọ ko wọ ninu Ile ẹjọ giga julọ Eko ni owurọ ana ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi nigbati Ọgbẹni M. A. Ọdẹsanya, ọkan ninu awọn Agbejọro ti o nṣẹnu fun Oloye Awolọwọ ninu Ile ẹjọ na lana niwaju Igbimọ ijoko awọn adajọ marun ti o ngbọ ẹjọ Awolọwọ pe, Adajọ si ara le lọna nitoripe, ko gbọ ẹjọ ti Olujẹjọ ro.

Ọgbẹni Ọdẹsanya wa pe akiyesi ijoko awọn adajọ si oju ewe kọkanlelogun, (page 21) ninu iwe idajọ nibiti adajọ ti sọ wipe,

"Ọgbẹni S. J. Umorẹn lọ si Ghana ni igba mẹwa tabi Igba mejila, nitorina, o jẹbi ẹsun iditẹ si Ijọba nitoripe ko si ohun ti o le wa lọ si Ghana laiṣe iṣẹ ogun"

Ọgbẹni Ọdẹsanya ni ẹjọ ti Umoren ro niwaju adajọ ni wipe, "Nigbati mo lọ si Ghana ni ọjọ kọkanlelogun oṣu kẹsan ọdun 1962, mo ri Ikoku ni Ghana ni igba mẹwa tabi mejila."

Ọgbẹni Ọdẹsanya ni, adajọ ro wipe igba mejila ni Umoren lọ si Ghana, o wa ṣe alaye pe igba kanṣoṣo pere ni Ọgbẹni Umoren sọ pe on lọ si Ghana ninu ọdun 1962.



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

Ọgbẹni Ọdẹsanya ṣe alaye pe, adajọ Agba Ṣowẹmimọ ro pe, igba mejila ni Umorẹn lọ si Ghana nigbati o jẹ wipe, igba kanṣoṣo ni Umoren lọ si Ghana.



Ọlọla Ade. Ademọla

Nigbati Abajọ Agba Ọlọla Adetokunbọ Ademọla ka iwe idajọ na tan, o wa bere lọwọ Ọgbẹni Ọdẹsanya pe "Iwe aṣẹ irinna Ọgbẹni Umoren da ?"

Ọgbeni Ọdẹsanya da adajọ lohun pe, 'Oluwa mi, ko si iwe aṣẹ irinna olujẹjọ na nihin, awọn abanirojọ ko tilẹ bere iwe na lọwọ rẹ ti nwọn fi ragabu rẹ."

### IBỌN POKITI

Ọgbẹni Ọdẹsanya tun ṣe alaye siwaju pe, nigbati awọn Ọlọpa fi mu olujẹjọ, nṣe ni nwọn nhalẹ mọ wọn nigba miran Ọgbẹni Ọdẹsanya ṣe alaye siwaju pe awọn ọlọpa a ma a yọ ibọn pokiti jade ninu apo pe ki awọn enia na o ma sọ ohun ti nwọn ba ri.

O tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe ki iṣe eyi nikan, nigba miran, awọn ọlọpa nsọ fun awọn enia na pe. "Awọn kan ti da orukọ rẹ pe Awolọwọ rano lọ si Ghana lati lọ kọ iṣẹ ogun, ti o ba le jẹwọ, ao fi ọ silẹ, sọ otitọ ẹmi rẹ ki iya o ma ba se jẹ ọ.

O ni nigba miran, awọn ọlọpa a gbe ọwọ soke pe "ti o ba sọ otiti, ngo gba ọ ni eti o" nipa bayi, jinnijinni da bo awọn enia na ti o fi jẹ wipe awọn ọlọpa ndawọn riboribo kakiri.

Ọgbẹni Ọdẹsanya tun ṣe afikun ninu ọrọ pe. Awọn ọlọpa a ma a kọ oju ibọn si awọn enia pe, jẹwọ o, ti o ba jẹwọ ao yiu ọ nibọn ṣugbọn ti o ba jẹwọ, were ni ao fi ọ silẹ"

O ni nigba miran, oniruru enia lo wa bere ọrọ lẹnu wọn pe, ti awọn olujẹjọ na ba jẹwọ awọn yio sọ fun Ijọba pe ki nwọn ma a lọ layọ ati alafia"

### OFIN PAJAWIRI

Ọgbẹni Ọdẹsanya wa rọ ijoko awọn adajọ na pe ki nwọn fi oju inu wo iru fitina ti awọn Ọlọpa fi on awọn olujẹjọ na ri ni asiko na.



Ọgbẹni M. A. Ọdẹsanya

O tun ṣe alaye pe, "ni asiko ti awọn Ọlọpa nle awọn enia na kakiri bi adiẹ

(Wo oju ewe kẹfa)

# BARIKA — DE — SALLAH

MO ba ẹnyin ọmọ iya mi ninu ẹsin Igba Ọlọrun gbọ ninu ẹmi yọ pupọ alaja ọdun Ileya yi. Bi ẹnikan ko ba tilẹ ni owo lọwọ ti Ọlọrun ba ti da ẹmi rẹ si di ọdun kan, o yẹ ki a ma yọ fun ilera ara wa. fun lehin gba nipa ẹ̀ Anabi Isa.

## Lati Ọwọ Ọgbẹni S. O. Jaiye, Eko

Lọna keji, ẹniti o ba sin Ọlọrun ti o si npe orukọ Rẹ si ọna ododo, o yẹ ki a gba ẹni na bi ara ninu ẹsin. Fun idi ẹsin iforibalẹ fun Ọlọrun nigba marun lojumọ, eyi ni pe, ninu ọdun kan iforibalẹ fun Ọlọrun jẹ 1825.

Bakanna Aawẹ fun ọgbọn ọjọ ninu ọdun kan. A ko le ma a sọ iru awọn aawẹ pẹẹpẹpẹ to tun wa fun iṣẹra ẹni. Gbogbo iṣẹra ẹni wọnyi ni mo ro pọ ti mo si mba nyin yọ ninu ẹmi ye, ẹ ku ọdun, ẹ si ku aṣepẹ ọdun o.

Lori iṣẹra ẹni Aawẹ fun ọgbọn ọjọ ati iru awọn nkan iṣẹra ni esin imọ Ọlọrun mbere lọwọ ẹnikokan ati Ọkunrin ati obinrin ati ọmọde ni ati agba ni mo fi mba nyin yọ pe ẹ ku odun, ẹ ku iyedun ki Ọlorun ko ṣe odun lauo fun gbogbo wa. Ti a ba wi bayi, itumọ eyi ni pe ki bi ohun ẹrọ fun gbogbo wa.

### ỌRỌ IṢIN A

Woli Muhammed, ikẹ ati Ọla Oluwa Ọba ko mọ ba gbe. Emi paapa, ninu aimọkan mi, mo gba ni adura gẹgẹbi ẹnyin paapa na ti ma a nwi lati fi yobo Woli na. Gẹgẹbi ohun ti mo fi eti mi gbọ lenu awọn to nkede waṣi ati kika ọrọ Korani lati maa fi ṣe omi toro ọrọ ti Ọlọrun ran si awọn enia rẹ ni aiye igba ini, eyi ni aiye atijọ.

O jẹ ohun iṣoro fun mi lati sọrọ odi si Woli Ọlọrun. Nigbati mo ba iye enia ni gbogbo aiye ti o ntẹle ẹnikan bayi ti nwọn si njẹwọ rẹ wipe, Woli ni iṣe, ko ni yẹ fun mi lati ma gba bi ẹni pataki.

Eyi ni pe gbogbo awọn Olutẹle ẹṣin yi jẹ ọdunrun le adọta ọkẹ (350, 000, 000)

Nitorina, gbogbo awọn Olutẹle wọnyi ko le sina tan rara. Botilẹ jẹ wipe, awọn Olutẹle Ẹsin Imale yi gba ọrọ inu Kurani wọn bi aṣẹ lori ẹsin wọn, ṣugbọn ọpọ isina lo wa ninu gbogba ọrọ Mimọ yi.

Mo tọrọ gafara lọwọ onkawe fun iladi awọn diẹ ti mo ri ninu ọrọ yi.

### OLUTẸLE ỌLỌRUN

Gẹgẹ bi ọro Ẹṣin ti jẹ ohun to lumọ eri ọkan, eyi ti ko ya ki ẹnikan wa larin ẹni ati Ọlọrun. Mo si ri nigba pupọ pe, nibiti a ti dogidi lali fi tabi la ọrọ Ọlọrun ye ara wa. aṣiṣe pupọ a ma wa ninu alaye ọrọ Ọlọrun.

Bẹni ọro Ọlọrun sọ pe a ko gbọdọ fi kun ọrọ on tabi kia mu kuro ninu ọrọ. fun idi eyi, ewu pupọ lo wa fun awa olutẹle ẹsin Ọlọrun lẹhin.

Gbogbo awọn olutẹlẹ Mohemmed lẹhin gba wpe Woli Ọlọrun ni Anabi Isa(Jesu) Nwọn nsọ lẹnu wipe ko si Woli ti Ibi Rẹ, Iṣẹ Rẹ, ati opin Rẹ ri bi ti Anabi yi

Nwọn gba wipe Iya Re ko sun mọ ọkunrin ki a to bi si aiye Nwọn tun gba wipe nikẹhin ọjọ Woli kan na ni yo ṣe idajọ aiye.

Nwọn tun gba pe o tun pada bọ wa si aiye. Gbogbo nkan pataki wọnyi ni olutẹle Ẹsin Mohemmed



Ọgbẹni S. O. JAIYE

Ṣugbọn ọpọ ninu ọrọ to jade ninu ọrọ koran ni nwọn nyi kiri fun ọgbọn ori wọn eyi ti ko dara to.

### AṢE ỌLỌRUN

Ọrọ Ọlọrun sọ pe "Lorukọ Anabi Isa ni ki gbogbo Ekun ma kunlẹ Gbogbo ẹniti o wa loke ọrun, eyi ti o wa ni orilẹ ati eyi to wa ni iṣalẹ ilẹ.

Bakanna ọrọ Ọlọrun wipe ko si orukọ kan ti a fun wa labẹ ọrun ti a le fi gba wa la a fi orukọ Anabi Isa Sibẹ ọpọ lo nka awọn ọrọ wọnyi ti nwọn si mọ Ṣugbọn nwọn ko hu iwa rẹ. Eyi ko dara ninu Ẹsin rara.

Gbogbo nkan to wa lode aiye ni a le gbiyanju lati yi pada Ṣugbọn a ko le yi Ododo Ọlọrun pada rara O yẹ ki a ṣọra pupọ ninu Ẹsin wa.

### ONIBARANDA

Bi mo ti nki awọn arakunrin mi ninu Ẹsin ku yedun ni mo tun pe akiyesi wọn si awọn ọrọ pataki yi, Bi mo ti nkiri ode ni mo nri awọn ẹran aguntan ti nwọn nda kiri.

Bẹni mo ri awọn ọmọde ti nwọn fi awọn agbo wọnyi ka kiri bi ohun iṣere iwo miran nyọ foti nibiti nwọn nkan ara wọn,

Elomiran ninu awọn ọmọde pa ẹran obi wọn ti nwọn fi owo ọpọ ra boya nipa fifi ebi para wọn ki nwọn to ko owo jọ fun ati ra awọn agbo wọnyi.

Bakanna ni Arapa ni mo ri ọpọ awọn onibarada ti o nba awọn ẹlẹran to ọja

Wo Oju Ewe Karun

## Bẹnson Sọ Pe On Mura Fun Ibo Didi

EKo:— Alakoso eto Irohin fun Ijọba Apapọ ti ilẹ Naijiria, Ọgbẹni T. O. S. Bẹnson sọ ninu ọrọ rẹ pe gẹgẹbi awọn enia kan ti npariwo on kakiri ati pe bi wọn si ti nsọ pe ki on fi ipo on silẹ gẹgẹ bi alakoso eto irohin fun Ijọba Apapọ ati lati lo fun eto idibo tuntun.

Ọgbẹni Benson si sọ pe ẹru ko ba on rara atipe ni agbara Ọlọrun on yio tun pada si ile igbimọ asofin ti ilẹ Naijiria ninu ọdun 1965.

Ọgbẹni Benson si tun sọ ninu ọrọ rẹ pe on gba pe gbogbo ọrọ ti awọn enia na nsọ ninu ọsẹ to kọja pe ki on fi aye na silẹ gẹgẹbi ere patapata Ọgbẹni Benson si tun sọ si pe on dibo gẹgẹbi ọmọ ẹgbẹ NCNC on si wọle ibo na atipe ko ṣe ti ẹgbẹ kankan rara gẹgẹbi ẹgbẹ ọmọ Ibo atipe awọn ẹgbẹ ọmọ Ibo to si nsọ pe ki on fi ipo on silẹ ko si aṣẹ lati sọ bẹ fun on.

Ọgbẹni Benson si tun ke si awọn amofin lati ṣe idabo bo on nitori awọn kan to si nkegbe on kiri ati pe wọn si le ṣe jamba fun on.

Ọgbẹni Benson si sọ pe on si ni igbẹkẹle pe ọpọlọpọ awọn enia Ipinlẹ Ila Orun lo si jẹ enia re re ati irẹpọ ilẹ Naijiria papa julọ ninu ẹgbẹ awọn ọmọ Ibo ti ko fi ara mọ gbogbo iyasọtọ awọn enia ilu kan.

Ọgbẹni Benson si tun sọ pe fun gbogbo ọrọ ti Olotu Apapọ Ijọba Naijiri a sọ nipa iyasọtọ awọn ilu kan



Ọgbẹni T. O. S. BENSON

ti o si sọ fun gbogbo aiye lati ni iṣọkan ni awọn ọmọ ẹgbẹ Ibo si tun ṣe lati ba On ja.

Ọgbẹni Benson si rọ awọn enia rere lati ke si awọn ọmọ ẹgbẹ na lati dakẹ gbogbo awọn iru ọrọ bayi eyi to o si tun fẹ jẹ aṣeju.

Ọgbẹni Benson si tun sọ pe nipa ọrọ On akọkọ ti On ko sọ si awọn ọmọ ẹgbẹ Ibo ti wọn si tẹ jade pe ko si ibikan ti on ti bu ẹnu atẹ lu awọn ẹgbẹ na gẹgẹ Ju ti ilẹ Naijiria, olotu

Wo Oju Ewe Karun

# IWE SI OLOTU

## Oloye Titus Balogun Nkọ ?

Mba ṣọpẹ bi Olotu Iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye niwọn iba ranpẹ ninu iwe re oloyinmọmọ lati bere Oloye Titus Ade Balogun ti iṣe akọwe ẹgbẹ N. P. C. fun gbogbo ilẹ Igbomina, nitoripe ti a ba ti ri ara ẹni tipẹ, o yẹ ki a le bere ara wa.

O fẹrẹ to oṣu mẹrin Oyinbo sẹhin nisisiyi ti a ti ri ọrọ Oloye Titus Balogun ka ninu iwe Irohin Imọlẹ.

Awa ọmọ Awẹ feran lati ma a ka ọrọ Oloye na, nitori ẹkọ, ọgbọn, oye ati ọrọ laakaye ni Balogun ma a sọ nigbagbogbo.

Inu mi yio dun bi Olotu ba le sọ fun wa mbi ti Oloye Balogun lọ



Oloye Titus Balogun

A si ran be Olotu ki o ba wa kọwe si i ki o le tun ma a sọrọ rẹ sinu iwe Irohin Imọlẹ.

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi, iwaju ni ọpa ẹbiti nyin yio ma a re si o.

Emi ni,
J. A. ADESHILẸ,
Awẹ.

## Eyi kO Ye Mi

Olotu ẹ ran mi lọwọ lati ba mi tẹ ibere mi yi jade fun awọn ọjọgbọn ti ori pe, ti o nka iwe nyin nfi ojojumọ ki wọn le tumọ ọrọ yi fun mi. Ọrọ na ru mi lojugan ni.

Mo nfẹ iyawo kan, Obinrin na si ntọ ọmọ lọwọ bi ko ba ri ko le jẹ bi ko ba ri mi ko le mu bẹ na ni emi na ti nba ri emi ko le ṣe nkan kan.

Nigbati ọmọ rẹ wọn o di pe bi mo ba ki ko tun da mi lohun mọ mo ro ọrọ na titi o su mi ni mo ba lọ fi ọrọ na lẹ iya rẹ. obinrin na si ṣe enia o da mi lohun pe o maṣe o emi ko le fẹ ọmọ oo.

Mo si ti na owo pupọ fun ọmọ obinrin na, ibere mi ni pe bawo ni mo tile ṣe lati gba owo ti mo ti na fun p da? ọrọ re, o enyin ọjọgbọn ti nka iwe Irohin Imọlẹ.

Emi ni
J. K. OLAWỌLE
Igbomina.

## Iwo nfẹ ile Ẹkọ

Ẹ dakun, ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ ti njade lojojumọ lati kesi awọn ọmọ ilu Iwo to wa nile ati loko jẹ ki a pe ara ati ẹdọfin inu wa lati ba sọ ojulowo ọrọ. Asiko lati tun ilu wa ṣe ki o le ba awọn ilu nla toku dọgba.

Otito ọjọ mẹlokan ti a ti ngbọ wipe Ijọba Ibilẹ Iwo yio kọ ile-ẹkọ giga ti awọn obinrin si Iwo, ṣugbọ a ko gbọ lilọ ati abọ ọrọ na mọ titi di bi mo ti nkọwe lọwọ yi.

Ilu Iwo ko kere larin awọn ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria, afẹ ki Ijọba Ibile Iwo ki o mọ sun gbagbe awọn ọmọ ti nbọ wa lẹhin ọla, gbogbo ilu ti koto bi to Iwo yi o ni ile-ẹkọ giga fun awọn obinrin.

A ni awọn Olukọ to le ṣe iṣẹ na, nwọn wa lọtun nwọn si tun wa losi, a fi bi a ko ba polowo iru enia ti a nfẹ sinu iwe irohin ni a o le ri awọn ọmọ ti ti o yege ẹkọ nla.

Mo bẹ enyin ọmọ Iwo nitoripe eniti o ba ran arare lọwọ ni Ọlọrun ranlọwọ. Bi a ba le mu ra si awọn nkan wa nigbana ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun yio to ran wa lọwọ.

Emi ni,
LALEKAN
Iwo

## Ọjọ Wo Ni Ileya Bọsi

Inu mi yio dun bi olotu ba le ran mi lọwọ lati tẹ ibere mi yi jade ninu iwe irohi Imọlẹ ki nwọn si fun mi ni esi to ba ibere mi na mu. Nitoripe mo mọ pe awọn ti o ri wọn pe ni o nka iwe na,

Ẹ jọwọ ọjọ wo ni awọn o ṣe ọdun Ileya n ọdun yi, A wọn kan ni ọjọ kẹrindinlọgbọn 26/4/64 oṣu yi ni awọn miran ni ọjọ kejilelogun (22/4/64) oṣu yi ni ko ye mi rara emi ko mọ bi nba ma mura silẹ fun ọdun Ileya,

Mo bẹ gbogbo ẹnyin ọjọgbọn ti ẹ ka Irohin Imọlẹ ki ẹ ki a mọ asiko ti a o ṣe ọdun ti ọdun ni, Mo tun bẹ ẹnyin Musulumi pẹẹ ẹjẹ ki a mọ ọjọ ti a ma ṣe ọdun Ileya ti ọdun yi o.

Olorun ajinde ara yio ma ṣe

Emi ni
Jimọh Kọlawọle
Ajaṣẹ-Ipo

## Egbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu yi (26/4/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

A o si yan awọn Alaṣẹ ẹgbẹ titun, eyi ti gbogbo ipade ti fi ohun sọkan lari yan ninu ipade ti a ṣe gbẹhin yi. Nitorina maṣe alai ko wa, boya oye na le kan ọ.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Adele Akọwe


## Congreve.s Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ekọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu ara tabi aikotọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi - oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, ẹfọri abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo Obinrin gegebi Ajo fun ilera ati orisirisi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni iu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọki egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ aju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orerẹ lukuluku onigbameji ti a ipẹri nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati orişirişi omiru pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

XXXX X

BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*

# Ę BAMI RĘRIN DIĘ

Lati ọwọ ĘṢỌ, Ajegunlę Apapọ.

Nigba aiye ijọun Arę Ọmọkakafo ti ile Ijaiye ję Alagbara Ologun, ati ijoye. Arę ję ijoye kan ti o ni ẹru pupọ ninu awọn ijoye Alafin.

Nigbati Arę ba nkọja lọ lode Ijaiye, awọn ẹru rę ati awọn ẹmẹwa rę a ma gbaruku tọọ lęhin, gbogbo ọrọ ti awọn wọnyi ba si sọ fun ni o ma ngba si otitọ.

Li apęrę, bi awọn ba sọ fun Arę wipe, li ana nigbati on kọja lọ, mo ri Lag aja ọmọ tamedu, nşe li o duro tandidi, ko tile fi ọpe kinikan loju rę. Nigba na Arę yio ran Onişe si i wipe ki oluwarę yara wa fi oju kan on.

Ęniti nwọn ran lọ pe, yio ma ko sinu igba, yio ma ko sinu awọn. Ęyi na lo di owe ti nwọn npa titi di oni bayi wipe, Arę npe ọ, o ndifa, bi Ifa tirę ba fọ ire ti Arę si fọ ibi nkọ. Bibę ni yio si bę oluwarę lori.

Nitori idi eyi, bi arę ba nkọjalọ. ati ọmọde ati agba o ma ndọbalę ki, Arę paapa ko ndahun a yafi awọn ẹmẹwa rę ti yio ma dahun wipe, o ki ọ, o ki ọ, o ki ọ. Nşe ni gbogbo enia nwariri nigbati nwọn baa gbọ oruko Arę, ijaiya si mu wọn,

Lakoko na ọmọ kekere akn wa nile Ijaiye ti oru kọ re nię Adesun, ko mọ oru eniti nwọn npe ni Arę o mbę lọdo baba rę nigbati awọn Alejo wa ki baba rę na, awọn alejo na rohin fun baba Adesun nọn ti Arę şe fun awọn ti ko ki i nigbati o nkọja lọ ladugbo na,

Fara ti ọmọ na dahun, o wipe, Baba! Nigbati Are ba tun kọja nihin nko ni kii. Baba re da lohun wipe ọmọbe ti ko ki Arę sisimi ni Arę isinmi. Agbalagba ti ko ki 'Arę sinsinmi ni Arę nsinmi. Kinni Arę yio fi kiki tirę şe ni gbogbo wọn ba ku si ẹrin ha, ha, ha, he, he, he, hu, hu, hu.

## ★ YĘ IRAWỌ RĘ WO ★

AQUARIAS (Jan 20 - Feb 18) Ara rę yio gbe kankan. iwọ yio si bori işoro gbogbo loni, Ọjọ oni dara lati fi gbọ tara rę, ọwọ rę yio si te owo dię loni

PISCES (Feb 19-Mar 20 ) Arę yio mu ọ loni, ko si işę kan ti yio wu ọ şe. bi o ba ję bę mașe fọwọ le ohun titun kan ni şişe bi koșe pe, ki o tọju ara rę. ko si şe faaji lori awọn ọrę rę.

ARIBS (Mar 21-April 19 ) Mura si işę rę loni ki o ba le ri owo dię, tun ara rę șe, bi bękọ, işę rę le daru.

TAURUS (April 20-May 21-) Ohun iyanu kan ti iwọ ko ro tęlę yio yọ si ọ loni.

GEMINI (May 22-Jun 21-) Ohun ayọ nla le yọ si ọ loni ni pa biba awọn gbajumo rin. Ohun titun kan yio şẹle si o loni

CANCER (Jun 22 July 23-) Orire yio de si ọ lọjọ ti oni bi o ba si ni iyawo, ipade iwọ pęlu rę loni yio ję ti orire.

LEO (July 24-Aug 23) Bi iwọ pęlu obinrin ba şere ipe papọ loni, aşę yio gori re' mura silę ni ọjọrọ

VIRGO (Aug 24-Sept 23) Şọra loni, ki ęwun ọkan ma ba mu ọ ra nkan ti iwọ'ko fe ra.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Arisiki rę fi ohun ti o dara han ọ şugbọn mașe fi owo ba ęnikan şere rara.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Fi ọrọ ara rę silę ki o ra ti awọn ęgbę ti o fę ba şe nkan papọ ni irọlę oni.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Ọjọ oni dara fun ęniti koiti ni iyawo nile. gęgębi irę bayi nwọn o si ma sọrọ rę nitirere.

CAPRICORN (Dec 23-Jan 19) Bi o ba rin irin ajo oni orire yio kan o.

AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An id-Ul-Kabir Dance**

AT

**FORESTER CENTERY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th Apri 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing,

**Tickets: 4/- Flat**

Tickets now on sale at 3, Olușhi Street Lagos 16, Bamgbọșe Street, Irohin Imọlę's Office Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANŞE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn

**RICHALET**

Rọbi-rọbi. Işę rę lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ĘJĘ ARA' bi Mọn mọnọ

FUN ARUN ĘJĘ ARA ENIA GBOGBO




Meji rę ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe n TỌNIKI Ęę ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilę ko di owo Iyẹn şe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lę yi,

Gęgębi awọn Onibara wa ti mọ irufę awọn egbogi ba awọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranşę fun tita lati awọn ilu Jamani, Faraose ati ti awọn Iatambulu si Itali ję

Mọ daju pe, bi ęję ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju şuşu tabi didun, Jędiędi Akọba, arun Ędọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalap Egbogi-n Amodi Apo ile ilọ, ęhin didu tabi ibaradi riro pęlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba ęję ara rę patapata yio si ni ęję rę mọ tonitoni pęlu.

Şa dan igo rę kan wo iwọ yio si ma a rohin rę fun ęlomiran pęlu

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 586 WEDNESDAY, APRIL 22, 1964 (2D)

## Awọn Danadana Da Reluwe Kan Duro

LONDỌNU:- Ha! ṣe gbogbo awọn enia to pe sile ẹjọ nla kan ni Ilu Londọnu nigbati adajọ ile ẹjọ nla idajọ rẹ fun awọn ọdaran mejila kan lori ẹsun ti Ọlọpa fi kan wọn lori iwa danadana ti nwọn hu ninu oṣu Kejọ ọdun ti okọja yi.

Ẹsun ti awọn Ọlọpa fi kan awọn ọdaran na ni pe, awọn da ọkọ Reluwe kan ti nko awọn lẹta lọ duro lọna Glasgow si Londọnu loru nwọn si ji owo ti oto adojc ọkẹ £2,600 000 gbe ninu ọkọ Reluwe na, nigbati nwọn da a duro.

Adajọ sọ awọn meji si ẹwọn ọdun mẹdọgbọn -mẹdọgbọn, awọn meje si ẹwọn ọgbọgbọn ọdun, ẹlomiran ẹwọn ọdun mẹrinlelogun, ogun ọdun ati bẹẹ bẹ lọ.

Awọn meje to gba ẹwọn Ọgbọgbọn ni Ronald Arthur eni ọdun mẹrinlegbọn onṣẹṣẹ gbẹnagbẹna, Charles Frederick Wilson eni ọdun mọkanlelọgbọn o nṣe iwe, Robert Welch, eni ọdun mẹrinlelọgbọn, o ntọju ile ero, James Hussey, ọgbọn ọdun o kun ile, Thomas Williams Wisbey, ọdun mẹtalelọgbọn o nṣe iwe, Roy John James ọdun mejidinlọgbọn o nwa mọto ere-ije ati Douglas Gordon Goody ọdun mẹrinlelọgbọn.

Brian Arthus Field, ọdun mọkandinlọgbọn akọwe agbẹjọrọ ati Leonard Dennis Field oṣiṣẹ ninu ọkọ oju-omi ẹwọn ọdun mẹdọgbọn-mẹdọgbọn.

William Boal, adọta ọdun eniti o ntun nrin ṣe gba idajọ ẹwọn ọdun mẹrinlelogun ati Roger Denby Cordrey ọdun mejilelogoji o ntọju ododo ẹwọn ogun ọdun ati John Denby Wheater ọdun mọkanlelogun gba idajọ ọdun mẹta.

# AWỌN KAN TI ILẸKUN ṢỌỌṢI !

## Awọn Ibo Ko Ri Aye Ṣe Isin

MUSHIN:— Ọjọ buruku eṣu bu omi mu ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu kẹrin ọdun yi jẹ fun awọn ọmọ ilu Ibo to jẹ ọmọ Ijọ C.M.S. Idi-oro Mushin, nigbati nwọn de ile Ọlọrun „Saint Paul Anglican Church" ti gbogbo ilẹkun ibẹ jẹ titi nwọn sare sọtun nwọn sare sosi, epa ko ba oro mọ. Nwọn lọ wo oniwasu nile nwọn kori nwọn tun lọ si ile awọn agbagba Ijọ omi ẹkọ ẹkọ na ni ọrọ jasi fun wọn.

Oniwe irohin wa fi ye wa pe ninu ile Ọlọrun yi ni awọn Yoruba ati Ibo ti jijọ ma nṣe isin papọ tẹlẹ awọn Yoruba ni yio kọkọ wa ṣe isin ti wọn ki awọn Ibo to wa ṣe tiwọn, ti awọn Yoruba ba ti pari isin wọn tan nwọn ko niti ilẹkun rara ti nwọn yio si ba ọna ile wọn lọ.

Ṣugbọn ni ọjọ yi bi awọn Yoruba ti jọsin tan ni nwọn ba ti ilẹkun ile Ọlọrun na pa patapata ti nwọn si ba ọna ilewọn lọ.

Nitotọ Yoruba ni o kọ ile Ọlọrun na fun arawọn, osi ti to ọdun mejidinlogun ti awọn Ibo ti nlo ile Ọlọrun na, o wa ya tan wọn lẹnu bi ọrọ na ti ṣe bọwọ sori ni ọjọ na. Nigbati nwọn ko ri ojutu rẹ diẹ ninu awọn enia na lo ṣe isin wọn nigbangba ita nigbati awọn miran lọ si Yaba lọ jọsin.

Irohin tun fi ye wa pe, nkan ti o fa titi ile Ọlọrun na ni ọrọ pe Ibo nyan Yoruba jẹ ti awọn ẹgbẹ oṣelu kan nfa mọ ara wọn, lọwọ lo tun de inu ijọ Ọlọrun.

Bisọbu ilu Eko, Alufa Eniọwọ Kalẹ ti ṣe kilọkilọ fun wọn pe, iwa eyi ki ṣe ara ilu mi, nwọn gbọdọ fi ọwọ rẹ bọlẹ, ọkanna ni gbogbo wa jẹ ninu Ijọ Ọlọrun,

Lọgan awọn ẹnia na ti da owo ti o to (ẹgbaji) pọnun (4,000) ni ọjọ na lati kọ ile Ọlọrun fun ara wọn. Awọn Ibo sọ pe oya awọn lẹnu fun iru iwa ti Yoruba Onigbagbọ ẹgbẹ awọn hu si awọn lori isin Ọlọrun.

## In Memoriam OF



Our Late Sister, Mrs. Victoria Adebisi Odukoya who died on 22/4/63.

R. I. P.

Chiefs Mr. & Mrs. D. A. Ajagbe
Children (1) ADEKUNLE
(2) FỌLASADE

Age She was born on October 23 1928 She died on April 22 1963.

Chief Mr. D. A. Ajagbe & Chief Mrs. Esther Adetonke, Ajagbe.

## Adajọ Si Ara Rẹ Lọna

Lati Oju Ewe Kini

irona ti o bọsilẹ ninu ago yi ni ofin pajawiri wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria."

O tun rọ ile ẹjọ pe ki awọn enia na o mọ wipe kabokabo ni gbogbo awọn enia na yio ma a sọ ni asiko yi, nitori gbogbo rudurudu to wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni asiko na.

O tun rọ adajọ lati gba pẹlu on, ati pe gbogbo enití wahala aiye ba ti ba ri, oluwarẹ yio mọ ohun ti nwọn npe ni kabokabo.

Ọgbẹni Ọdẹsanya tun ṣe alaye pe, o lodi si ofin ati gba ẹjọ lẹnu eniti Ọlọpa ti fi pamọ sinu itimọlẹ tabi ogba ẹwọn

O tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, ki awọn Ọlọpa o to le ti enia kan mọle, nwọn gbọdọ kọkọ gba ọrọ kọ silẹ lẹnu rẹ na, nigbati o ba sọ ọrọ ẹnu rẹ, ti awọn Ọlọpa ba si ti kọ awọn ọrọ na sinu iwe wọn tan, ni nwọn to le ti oluwarẹ mọle.

Siwaju si i, o ni bi Ọlọpa ba ti enikan mọle, nwọn le bere ọrọ lọwọ rẹ, lati fi ma a ba iwadi wọn lọ lori ẹsẹ ti oluwarẹ ba ṣe, ṣugbọn nwọn ko gbọdọ lọ kọ ohun ti o ba sọ ni itimọle silẹ nwọn ko gbọdọ gbe akọsilẹ ọrọ na wa si ile ẹjọ, ki nwọn ba si gbe e wa si ile ẹjọ adajọ ko gbọdọ gba ọrọ na gẹgẹbi ọrọ ti Ọdaran sọ.

Ọgbẹni Ọdẹsanya tun fi ye Ile ẹjọ pe, gbogbo ihale ti awọn ọlọpa se si awọn Olujẹjọ na lo da aiya ja ẹlomiran ti o fi ngbọn ti o si sọ ọrọ sọ.

Ọrọ yi ni ọgbẹni Odẹsanya sọ ni ile ẹjọ na ti agogo mẹwa owurọ fi lu, Ile ẹjọ na tuka ni dede agogo kan abọ osan, ijoko wọn si tun di ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn osu yi, ṣugbọn irohin ile ẹjọ na pọ ni ana, ẹ si ma a gbọ iyoku ni owurọ ọla O darọ.

GET A WATCH WITH A PERSONAL TOUCH
... IN YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL



Free illustrated catalogue on demand

Réf. N° 55. PHOTO

A Wonderful 15 Jewel lever shock protected movement, non magnetic, unbreakable mainspring. ROLLED GOLD waterproof case and stainless steel back with your name engraved. Beautiful diamond polish raised figures, luminous and YOUR PHOTO reproduced IN COLOR on metal dial.

PRICE £ 5.

HURRY SEND YOUR PHOTO (any size) with cash or cheque.

WINDSOR
19, Avenue de Lérins - Cannes, France

Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Ilangbose Street Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga 22/464